# JSS 3 YORÙBÁ LANGUAGE FIRST TERM NOTE

## AGBEKALE ISE TAAMU KIN-IN-NI FUN ODUN

| OSE | ORI-ORO | AKOONU |
|---|---|---|
| 1. | ASA:- Itan Isedale ati Itankale omo Yoruba | a. Itan bi Oduduwa se kuro ni Meka.<br>b. Irin-Ajo Oduduwa si Ile-Ife.<br>c. Awon omo ati omo-omo Oduduwa.<br>d. Itankale awon omo Yoruba. |
| 2. | EDE:- Fonetiiki ede Yoruba. | a. Iro ohun ede Yoruba.<br>b. Iro konsonanti<br>c. Iro faweli. |
| 3. | Asa:- ikini ati idahun | a. Ikini fun oniruuru igba ati akoko.<br>b. Ikini fun oniruuru ayeye.<br>c. Ikini fun oniruuru ise |
| 4. | Ede:- Akaye | a. Alaye lori akaye.<br>b. Awon atoka ibeere.<br>c. Kika ati didahun ibeere lori ayoka oloro geere.<br>d. Kika ati didahun ibeere lori ayoka onisorogbesi. |
| 5. | Ede:- Akoto Ode Oni | a. Alaye lori akoto.<br>b. Sipeli atijo ati ode-oni. |
| 6. | Ede:- Oro-Ayalo | a. Itumo oro-ayalo<br>b. Awon ede ti Yoruba ti ya oro lo.<br>c. Ona ti oro-ayalo gba wonu ede Yoruba.<br>d. Ote lori oro ayalo<br>e. Orisi oro-ayalo. |
| 7. | Litireso:- itupale iwe itan apileko. | a. Kika iwe itan apileko.<br>b. Itan inu iwe ni soki.<br>c. Awon eda itan<br>d. Koko eko inu iwe |
| 8. a.<br>b. | Ede:- Onka Yoruba;<br>Ede:- Isori-Oro: Oro-oruko | a. KIka 300 – 400 ni ede Yoruba.<br>b. Itumo pelu apeere oro-oruko.<br>c. Orisi oro-oruko.<br>d. Ise oro-oruko ninu gbolohun |
| 9. | Ede:- Itesiwaju Isori-oro | a. Oro-aropo-oruko (itumo pelu apeere)<br>b. Orisi oro-aropo-oruko.<br>c. Ise oro-aropo-oruko |
| 10. | Asa:- Owo sise ati ipolowo oja. | a. Alaye lori owo sise.<br>b. Itumo ati ohun ti a n polowo.<br>c. Ona ipolowo oja laye atijo ati ode oni. |
| 11. | Ede:- Iseda oro-oruko | a. Mofiimu ati orisi afomo<br>b. Oro ri a ko seda ati oro ti a seda.<br>c. Awon ona ti a n gba seda oro-oruko. |
| 12. | Ede:- Aroko kiko | a. Itumo ati orisii aroko<br>b. Apeere ori-oro fun aroko kookan.<br>c. Igbese aroko. |
| 13. | Atunyewo eko | Revision |

# Topic 1: Itan Isedale Awon Yoruba.

**1.0 Itan Bi Oduduwa se Kuro ni Meka.**

Ile-Ife ni orirun awon Yoruba.Oduduwa ni baba-nla awon Yoruba. Lamurudu ni baba Oduduwa.oba ati olori esin ibile ni Lamurudu je ni ilu Meka. Ija esin lo mu ki Oduduwa kuro ni Meka. Ninu ija esin ni Lamurudu ku si.

**1.1. Irin-Ajo Oduduwa si Ilu Ile-Ife.**

Aadorun ojo (90 days) ni Oduduwa ati awon eniyan re fi rin de Ile-Ife. Nitori aare awon kan ninu awon ibatan Oduduwa ko le rin de Ile-Ife. Awon Kukawa, Gogobiri ati Beriberi. Awon duro ni apa Oke-Oya, ni ile Sokoto ati Boronu.

**1.2. Ile-Ife Saaju Dide Oduduwa.**

Agbonniregun ni oba ati olori esin ni Ilu ile-Ife ki Oduduwa to de. Agbonniregun gba Oduduwa ati awon eniyan re towo-tese. Oduduwa ran ilu Ile-Ife lowo lati ja ati lati se opolopo ogun. Nigba ti Agbonniregun ku won fi oduduwa je oba ilu Ile-Ife.

**1.3. Awon Omo ati Omo-omo Oduduwa.**

Oduduwa bi omo kan ti oruko re n je Okanbi. Okanbi bi omo meje, omobinrin meji ati omokunrin marun-un. Nigba ti awon omo wonyi dagba won kuro ni Ile-Ife won si lo da ilu ti ara won sile. Bakan naa ni itan fi ye wa pe awon omo wonyi pin ogun baba won leyin iku won.

**1.4. Bi awon omo Okanbi se pin ogun baba won.**

| S/N | Omo Okanbi | Ilu ti won tedo | Ogun ti won pin |
|---|---|---|---|
| 1. | Olowu (obinrin) | Owu | Aso (cloth) |
| 2. | Alaketu (obinrin) | Ketu | Ade (Crown) |
| 3. | Oba Ibini | Bini | Owo-eyo (Cowries) |
| 4. | Orangun | Ila-Orangun | Iyawo (Wifes) |
| 5. | Onisabe | Sabe | Eran-osin (Animals) |
| 6. | Onipopo. | Popo | Ileke. (Beades) |
| 7. | Oranmiyan | Oyo | Ile. (Land) |

**1.5. Itankale Awon Omo Oduduwa**

Nigba ti awon omo wonyi dagba onikaluku lo te ilu ara re do. Oranmiyan te Ilu Oyo do o si di oba. Bayi ni awon omo yooku naa di oba ni ilu ti won tedo. Oranmiyan ni Alaafin akoko ni ilu Oyo. Leyin re ni omo re Ajaka je oba. Sango ni Alaafin keta ni ilu Oyo.

**1.6. Awon Oba Alade Ile Yoruba**

| | Oruko Oye | Ilu won. |
|---|---|---|
| 1. | Ooni | Ile-Ife |
| 2. | Alaafin | Oyo. |
| 3. | Ataoja | Osogbo |
| 4. | Alake | Ile Egba (Abeokuta) |
| 5. | Awujale | Ijebu-Ode |
| 6. | Akarigbo | Ijebu-Remo |
| 7. | Deji | Akure |
| 8. | Osemowe | Ondo |
| 9. | Ogiyan | Ejigbo |

| | | |
|---|---|---|
| 10. | Olubadan | Ibadan |
| 11. | Elekole | Ikole-Ekiti |
| 12. | Owa-Obokun | Ijesa land (Ilesa) |
| 13. | Oba | Eko. |
| 14. | Oluwoo. | Iwo. |
| 15. | Onirele | Irele |
| 16. | Orimolusi | Ijebu-Igbo |
| 17. | Oba Akanran | Badagry |

**INSTRUCTION MATERIALS; MAP OF AFRICA INDICATING THE JOURNEY OF ODUDUWA TO ILE-IFE**

Ise Kilaasi : Class Work

Di alafo wonyi pelu idahun ti o ye.

1. Baba-nla awon Yoruba ni _______ A. Lamurudu. B. Oduduwa. C. Agbonniregun
2. ________ ni orirun awon Yoruba. A. Meka. B. Ibadan. C. Ile-Ife.
3. Ojo meloo ni Oduduwa ati awon eniyan re fi rin de Ile-Ife? _____ojo. A. aadorin. B. aadorun-un. C. ogorin
4. Ta ni oba Ile-Ife ki Oduduwa to de? A. Obasanjo B. Okanbi C. Agbonniregun
5. Omo meloo ni Oduduwa bi? Omo ________ A. kan B. meji C. meta

Ise Asetilewa.

1. Daruko omo okanbi marun-un ati ogun ti won pin.
2. Ko oruko oye awon oba wonyi sile.
   a. Abeokuta
   b. Ile-Ife
   c. Ondo
   d. Oyo
   e. Ejigbo

## 2.0. Topic 2: Ede: Fonetiiki Ede Yoruba: Awon Iro Ede Yoruba.

**2.1. Awon Iro Ede Yoruba ni:**

a. Iro ohun
b. Iro konsonanti
c. Iro faweli.

**2.2. Iro Ohun; Iro ohun ni gbigbe ohun soke ati sodo ti o maa n waye ninu ede Yoruba nigba ti a ba n soro.**

2.3. **Orisi Iro Ohun**

1. Iro ohun oke – high tone
2. Iro ohun aarin – mid tone
3. Iro ohun isale – low tone

**2.4. Amin ohun ni a maa n fi si ori oro. Amin ohun meta inu ede Yoruba ni:**

   a. Ami ohun oke (m = /)

b. Ami ohun aarin (r = - )
c. Ami ohun isale (d = \)

**2.5. Akiyesi Nipa Ami Ohun**

1. Ori faweli ni a maa n fi ami ohun si. Awon faweli ohun ni airanmupe a, e, e, i, o ,o ,u ati aranmupe an, en, in, on, un.
2. A tun le fi ami ohun si ori konsonanti aranmu asesilebu. 'm' ati 'n'
3. A kii fi ami ohun siori konsonanti yooku : b d f g gb h j k l  p r s s t w y.
4. A kii fi ami ohun aarin sori oro.
5. Ami ohun oke kii bere oro Yoruba ajumolo ayafi eka ede.

**Fifi ami ohun si ori oro**

1. Ami ohun oke (m = /)
   a. m – wa – come
   b. m – si – open
   c. mm – sibi – spoon
   d. mm – pako – wood
   e. mmm – patako – board
   f. mmm – Kolade – a name
2. Ami ohun aarin (r = -)
   a. r – je – eat
   b. r – mu – drink
   c. rr – eja – fish
   d. rr – omi – water
   e. rrr – omoge - young beautiful girl
   f. rrr – agbada – fry pan
3. **Ami ohun isale**
   a. d – sun – sleep
   b. dd – epa – ground nut
   c. dd – eje – blood
   d. ddd –ogede – banana
   e. ddd – akaso – ladder
4. **Apapo Ami Ohun Meteeta**
   a. dm – eko – education
   b. rm – owo – money
   c. ddm – iyawo – wife
   d. dmr – ibepe – pawpaw
   e. rmdm – alakowe – an educated person
   f. ddrd – opolopo – many
5. **Awon Oro onisipeli kan naa ti ami ohun ya soto.**

   **a.**
   i. rm – oko - hoe
   ii. dd – oko – sword
   iii. rr – oko - husband
   iv. rd – oko – vehicle

   **b.**
   i. rm – igba - calabash
   ii. dd – igba - time
   iii. rr – igba – 200
   iv. dm – igba – garden egg
   v. rd – igba- climbing rope

   **c.**
   i. rm – agbon – wasp
   ii. rd – agbon - basket
   iii. dr – agbon - coconut
   iv. dm – agbon – a town

**2.7. Konsonanti ede Yoruba.**

2.7.1 Konsonanti ni iro ti a pe nigba ti idiwo wa fun eemi ni ibikan ni opona ajemohun. Awon konsonanti ede Yoruba ni; ***b d f g gb h j k l m n p r s s t w y.***

**2.7.2. Apejuwe Iro Konsonanti:** ona meta ni a le gba se apejuwe iro konsonanti:

a. Ibi isenipe – place of articulation
   i. Afejietepe: ***b, m***
   ii. Afeyinfetepe: ***f***
   iii. Aferigipe: ***t, d, s, n, r, l***
   iv. Afajaferigipe: ***j, s***
   v. Afajape: ***y***
   vi. Afafasepe: ***k, gb***
   vii. Afafasefetepe: ***p, gb, w***
   viii. Afitan-an-na-pe: ***h***

b. **Ona Isenupe – Manner of Articulation**
   i. Asenupe: ***b, t, d, k, g, p, gb***
   ii. Afunnupe: ***f, s, s, h***

iii. Asesi***: j***

iv. Aranmu: ***m, n***

v. Arehon***: r***

vi. Afegbe-enu-pe***: l***

vii. Aseesetan***: y,w***

**c. Ipo Tan-an-na**

i. Aikunyun: (voiceless sounds ):**f, s, s, h, p, t, k**

ii. Akunyun (voiced sounds): ***b, d, g, gb, j, m, n, p, r, w, y***

**2.7.2. Ate Konsonanti ede Yoruba.**

| Ibi isenupe | Afeji-ete-pe | | Afeyin-fetepe | | Aferigipe | | Afaja-ferigipe | | Afajape | | Afafasepe | | Afafase-fetepe | | Afitan-an-na-pe | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Ona isenupe | aik | ak | aik | ak | aik | ak | aik | ak | aik | ak | aik | ak | aik | ak | aik | ak |
| Asenupe | | ***b*** | | | ***t*** | ***d*** | | | | | ***K*** | ***g*** | **kp** | ***gb*** | | |
| Afunnupe | | | ***F*** | | ***S*** | | ***S*** | | | | | | | | ***h*** | |
| Asesi | | | | | | | | ***j*** | | | | | | | | |
| Aranmupe | | **m** | | | | ***n*** | | | | | | | | | | |
| Arehon | | | | | | ***r*** | | | | | | | | | | |
| Afegbeenupe | | | | | | ***l*** | | | | | | | | | | |
| Aseesetan | | | | | | | | | | ***y*** | | | | ***W*** | | |

**2.7.3. Apejuwe Iro Konsonanti**

i. *b*: afejietepe, asenupe, akunyun

ii. *m*: afejietepe, aranmupe, akunyun

iii. *f*: afeyinfetepe, afunnupe, aikunyun

iv. *d*: aferigipe, asenupe, akunyun.

v. *t*: aferigipe, asenupe, aikunyun

vi. *n*: aferigipe, aranmupe, akunyun.

vii. ***s***: aferigipe, afunnupe, aikunyun

viii. *r*: aferigipe, arehon akunyun.

ix. *l*: aferigipe, afegbeenupe, akunyun.

x. ***S***: afajaferigipe, afunnupe, aikunyun.

xi. **j**: afajaferigipe, asesi, akunyun

xii. ***y***: afajape, aseesetan, akunyun

xiii. **k**: afafasepe, asenupe, aikunyun.

xiv. ***g***: afafasepe, asenupe, akunyun.

xv. ***p***: afafasefetepe, asenupe, aikunyun.

xvi. ***gb***:afafasefetepe, asenupe, akunyun.

xvii. ***w***: afafasefetepe, aseesetan, akunyun

xviii. ***h***: afitan-an-nape, afunnupe, aikunyun

xix.

**2.8. Iro Faweli:** Eyi ni iro ti a pe nigba ti ko si idiwo fun eemi ni ibikan ni opona ajemohun. Apapo faweli ti o wa ninu ede Yoruba je mejila.

**2.9. Orisi Faweli**

a. **Faweli Airanmupe:** Eyi ni faweli ti a pe nigba ti afase di kaa imu ti eemi si gba enu jade. Faweli airanmupe meje lo wa ninu ede Yoruba.
Apeere: ***a, e, e, i, o, o, u.***

b. **Faweli Aranmupe:** Eyi ni faweli ti a pe nigba ti afase wa sile ti eemi si gba imu ati enu jade. Faweli aranmupe marun-un lo wa ninu ede Yoruba.
Apeere: an, en, in, on.
Eemi gba imu nikan jade nigba ti a pe ***'un'***

2.10. **Apejuwe Iro Faweli:** Ona marun-un ni a le gba se apejuwe iro faweli.

**a. Giga ahon si aja enu (height of the tongue)**

i. Oke : Ahanupe:- ***i, u, in, un***

ii. Ebake: Ahanudiepe:- ***e, o***

iii. Ebado: Ayanudiepe:- ***e, o, en, on***

iv. Odo: Ayanupe:- ***a, an***

**b. Abala ahon ti a lo*: Parts of the tongue***

***i.*** Iwaju ahon*:-I, e, e, in, en*

***ii.*** Aarin ahon*:= a, an*

***iii.*** Eyin ahon*:- u, o, o, un, on*

**c. Ipo ete: *Position of the lips***

***i.*** Perese*: I, e, e, a, ain, en, an*

***ii.*** Roboto*: u, o, o, un, on*

**d. Ipo afase*:- Position of the soft palate***

***i.*** Airanmupe*:- a e e i o o u*

***ii.*** Aranmupe*:- an en in on un*

**e. Ipo Tan-an-na*:- Position of the glottis.***

*Gbogbo faweli Yoruba ni akunyun.*

## *Ate Faweli Ede Yoruba*




## 2.11.Apejuwe Faweli Kookan

**i**:- airanmupe, ahanupe,oke, iwaju, perese

**a**:-airanmupe, ayanupe, odo, aarin, perese

**e**:- airanmupe, ahanudiepe, abake,iwaju, perese

**e**:- airanmupe, ayanudiepe, ebado, iwaju, perese

**o**:- airanmupe, ahanudiepe, ebake, eyin, roboto

**u**:- airanmupe, ahanupe, oke, eyin, roboto

**o**:- airanmupe, ayanudiepe, abado, roboto

**in**:- aranmupe, ahanupe, oke, iwaju, perese

**en**:- aranmupe, ayanudiepe, ebake, iwaju, perese.

**an**:- aranmupe, ayanupe, odo, aarin, perese.

**on**:- aranmupe, ayanudiepe, ebado, eyin roboto

**un**:-aranmupe, ahanupe, oke, eyin, roboto

**Ise Kilaasi: Class Work**

**Di alafo wonyi pelu idahun ti o ye.**

1. Konsonanti afejietepe ni ______
   A. f
   B. k
   C. b
2. Ewo ni ranmupe ninu konsonanti wonyi? ___
   A. m
   B. g
   C. r
3. Konsonanti ede Yoruba je ____
   A. mejilelogun
   B. majidinlogun.
   C. marundinlogbon.
4. Faweli iwaju ni ______
   A. o
   B. e
   C. u
5. Faweli aarin ayanupe odo perese ni _____
   A.i
   B.e
   C.a
6. Faweli roboto ebake ni ______
   A. u
   B. o
   C. e

**ISE ASETILEWA : ASSIGNMENT**

1. Se apejuwe awon konsonanti wonyi
   I. /f/
   II. /g/
   III. /k/
   IV. /w/
   V. /s/
2. Ya ate faweli ede Yoruba.

**TOPIC 3: IKINI ATI IDAHUN**

**1. IKINI FUN ONIRUURU IGBA ATI AKOKO**

| ***ENGLISH*** | ***YORUBA*** |
|---|---|
| 1. Good morning | 1. E kaaaro. |
| 2. Good afternoon. | 2. E kaasan. |
| 3. Good evening | 3. E kale. |
| 4. Good night. | 4. O daaro |
| 5. Good bye | 5. O dabo |
| 6. Welcome. | 6. E kaabo |
| 7. Welldone. | 7. E kuuse. |
| 8. Welldone at home | 8. E kuule. |
| 9. How are you? | 9. Bawo ni? |
| 10. How [s family? | 10. Ile nko? |
| 11. How is work? | 11. Ise nko? |
| 12. Thank you. | 12. E se a dupe |
| 13. I am sorry. | 13. Ma binu |
| 14. Please. | 14. E jowo. |

**Awon ikini miiran**

| ***Bawo ni a se n ki eniyan ni awon asiko wonyi?*** | Idahun |
|---|---|
| 1. Idaji | E ku idaji. |
| 2. Iyaleta | E ku iyaleta. |
| 3. Irole | E ku irole. |
| 4. Asiko oye | E ku oye. |
| 5. Asiko ooru | E ku ooru. |
| 6. Asiko ojo | E ku ojo/ |
| 7. Asiko ogbele | E ku ogbele. |
| 8. Asiko oginnitin | E ku oginnitin. |
| 9. Asiko odun titun | E ku odun titun. |
| 10. Asiko odun Keresimesi | E ku odun |

| | |
|---|---|
| 11. Asiko odun ajinde<br>12. Bawo ni a se n ki oba? | keresimesi.<br>E ku odun ajinde<br>Kaabiyesi o.<br>kade pe lori.<br>ki bata pe lese<br>igba odun odun<br>kan. |

**2. IKINI FUN ONIRUURU AYEYE**

Awon Yoruba ni ikini fun oniruuru ayeye bii isomoloruko, igbeyawo, isile, isinku agba, ojobii, oye jije, ile sisi ati bee bee lo.

| Ayeye | Ikini | Idahun |
|---|---|---|
| 1. Alaboyun | Asokale anfaani<br>Afon a gbo ko to wo | Ase. |
| 2. Onigbeyawo | E ku inawo iyawo.<br>Eyin iyawo ko ni mo eni. | E se, a dupe. Adun a kari. |
| 3. Olomo titun | E ku ewu omo.<br>E ku owo lomi. | E se a dupe<br>Adun a kari. |
| 4. Olojo ibi. | E ku ojobi. | E se a dupe. |
| 5. Eni to yege lenu ise. | E ku oriir.e | E se a dupe. |
| 6. Eni to ra oko titun. | E ku inawo oko. | E se a dupe. Adun a kari. |
| 7. Eni to ko ile titun. | E ku inawo ile. | E se a dupe. Adun a kari. |
| 8. Eni to je oye titun. | E ku inawo oye. Oye a mori | E se a dupe. Adun a kari. |
| 9. Eni ti ofo se. | E ku aseyinde. | E se a dupe. Ojo a jinna sira. |

**3. IKINI FUN ONIRUURU ISE**

| ISE | OSISE | OHUN ELO | IKINI | IDAHUN |
|---|---|---|---|---|
| 1. Ise agbe | Agbe | Ada ati oko | Arokobodunde | Ase |
| 2. Ise ode | Ode | Ibon, etu ati ota ibon | Arepa Ogun<br>Ogun a fowo jona | Ase.<br>Ogun a gbe o. |
| 3. Ise ope kiko | Akope | Igba ati aake. | Igba a ro. | Ase. |
| 4. Ise emu dida. | Ademu | Igba, aake, eya ati akeregbe | Igba a ro. | Ase. |
| 5. Ise irun didi. | Onidiri. | Ooya, owu ikorun ati adi agbon. | Oju gbooro. | Ooya a ya. |
| 6. Ise aro dida | Alaro | Aro, omi ati ikoko | Aredu o. | Iyamopo a gbe o. |
| 7. Ise agbede | Alagbede | Ewiri, omo owu ati eesan, | Aroye o. | Omo owu ni idahun re. |
| 8. Ise awo | Babalawo | Opele ati opon-ifa | Aboruboye o. | Aboruboye bo sise. |
| 9. Ise eja pipa. | Apeja. | Iwo, igere, ati awon | Owo a de o. | Ase. |
| 10. Ise oko wiwa. | Awako. | Oko tabi opon. | Awaye o. | Ase. |

**Ise kilaasi: Class Work**

**Di alafo wonyi pelu idahun ti o ye.**

1. Ki ni “Good moring” tumo si?______
   A. E kaasan
   B. E kaaaro
   C. e kaale
2. Ta ni a n ki pe E ku owo lomi? ______
   A. onigbeyawo
   B. olojo ibi
   C. olomo titun

3. Aboruboye je ikini fun ______
   A. babalawo
   B. agbe
   C. akope
4. Eni to n sise eja pipa ni a n pen i _____
   A. ademu
   B. awako
   C. apeja
5. Ohun elo ise agbe ni ____
   A. ada
   B. igba
   C. igere

Ise asetilewa.

1. Bawo ni a se n ki awon eniyan wonyi ni ede Yoruba?
   a. Alaboyun
   b. Akope
   c. Onidiri
   d. Alaro
   e. Agbe
2. Daruko ohun elo ise awon eniyan wonyi:
   a. Apeja
   b. Onidiri
   c. Akope
   d. Agbe
   e. babalawo

**TOPIC 4: AKAYE : COMPREHENSION**

Akaye ni kika aypka ni ona ti yoo gba ye eniyan yekeyeke ti a o si le dahun ibeere lori ayoka naa. Ki akekoo to le yege ninu ayoka o ni awon nnkan ti o gbodo kiyesi:

a. O gbodo ka ayoka naa ni igba meji tabi ju bee lo.
b. O gbodo salaye ohun ti ayoka dale lori.
c. O gbodo tumo awon oro to ta koko ninu ayoka naa.
d. O gbodo le fun ayoka naa ni akole ti o ba a mu.
e. O gbodo le ka ibeere lori ayoka ni akaye.

**Orisi Ayoka: A le pin ayoka si ona meji tabi meta:**

a. Ayoka Oloro Geere.
b. Ayoka Onisorogbesi.
c. Atoka Ewi. Note: (Ayoka meji ni a o se agbeyewo re ninu eko yii)

1. **Ayoka Oloro Geere**

**Ka ayoka isale yii ki o si dahun awon ibeere ti o tele e.**

Oriki se pataki ninu asa Yoruba. Oriki je ona ti awon Yoruba maa n fii yin ara won tabi eni ti inu won ba dun si.

Orisiirisii oriki ni o wa, oriki soki, inagije, alaje, oriki eranko, igi, oriki amutorunwa, oriki to ba oruko kookan lo, oriki borokinni ati oriki orile.

Bi a ba bi omo tutun ni ile Yoruba ojo kesan-an ni a maa n so omokunrin loruko. Ojo keje ni ti omobinrin. Ojo kejo ni ti awon ibeji to je tako-tabo. Sugbon laye ode oni ojo kejo ni a n so gbogbo omo loruko yala omokunrin tabi omobinrin.

Gbogbo igba ni a maa n ki oriki nile Yoruba. Oriki wa fun omode o wa fun agba, o wa fun olowo, o wa fun mekunnu, a fi n ki oba a si fi n ki ijoye. Oriki soki ni a maa n fun omo titun.

Igbagbo Yoruba ni pe omo ti won ba ki ni oriki idile won ori won maa n wu. Igba yii ni iru omo bee yoo maa rerin-in muse-muse. Ti o ba si je wi pe o n sun ekun lowo ni kia ti o ba n gbo oriki ni yoo dake jee. Eyi fihan gbangba pe awon omo ikoko naa maa n gbo oro ti won si tun mo pataki oriki.

**Dahun ibeere wonyi: (1 – 10)**

1. Igba wo ni a maa n se amulo oriki ni ile Yoruba?
   A. Gbogbo igba
   B. Osan
   C. Aaro
   D. Irole
2. Ojo keloo ni a n so omokunrin loruko nile Yoruba? Ojo
   A. Kejila
   B. Kokanla
   C. Kewaa
   D. Kesan-an
3. Oriki ti a maa n fun omo titun nu oriki
   A. Borokinni
   B. Eranko
   C. Orile
   D. Soki
4. Awon Yoruba maa n fi oriki ____ ara won.
   A. Yin
   B. Bu
   C. Sote
   D. Soge
5. Ewo ninu awon wonyi ni kii se oriki Yoruba? Oriki
   A. Amutorunwa
   B. Aworan
   C. Borokinni
   D. Eranko.
6. Awon Yoruba maa n so omobirin loruko ni ojo
   A. Kejo
   B. Keje
   C. Kesan-an
   D. Kewaa
7. Omo ti a n so loruko ni ojo kejo ni
   A. Alaba
   B. Taiwo
   C. Kehinde
   D. Ibeji tako-tabo
8. Ewo ni a ko daruko ninu awon oriki wonyi? Oriki
   A. Amutorunwa
   B. Borokinni
   C. Eranko
   D. Aga
9. Ohun tin o maa n je ki omo rerin-in muse-muse ni
   A. oriki
   B. oruko
   C. orin
   D. owe
10. akole ti o ba ayoka yii mu ju ni asa
    A. igbeyawo
    B. isinku
    C. oriki
    D. oge-sise

**2. AYOKA ONISOROGBESI:- DIALOGUE**

**Itakuroso: ka itakuroso isale yii ki o si dahun ibeere abe re.**

**iya agba**: E kaaaro o nibi. E ku owo lomi o.

**iya Seri**: O o, e seun o. ayo a kari.

**Iya agba**: Amin. Se ose aweda ti wa nile fun ikoko?

**Iya Seri**: Mo ti ran Sulia ko lo ra a lodo iya elepo.

**Abeni**: Mo sebi ose oyinbo ti a n lo naa ni won fi n we ikoko ni.

**Iya agba**: Rara o, ose aweda ti a tun n pe ni ose abuwe ni o dara ju fun omo titun.

**Abeni**: Bawo lo se ri? Se ose lile ni tabi lubulubu?

**Iya agba**: O kare Abeni. Ose naa ko ri bi ose lile ti a n fi beba pon, bee ni kii se lubulubu. Ki i le lowo pupo, o maa n dudu ni won se tun n pe e ni ose dudu. Ti a ba ti fi omi die won on maa n bu u diedie sara kaninkanin fun wiwe ni nitori o maa n ho ju ose oyinbo lo.

**Abeni**: Nibo ni ile-ise to se e wa?

**Iya agba**: Ni ebu ni awon obinrin ti n se ose yii sugbon ni abuke ati ilu kereje ni o ti wopo.

**Abeni**: Ki ni won fi n se ose yii?

**Iya agba**: Won n lo adi, eeru igi ti a ri lara soso eyin tabi padi koko. Won a tun maa lo omi pelu epo pupa.

**Abeni**: Ki ni ise ti ose yii n se?

**Iya agba**: Ose abuwe maa n dena kokoro ti o le ba awo ara je. A si maa mu ara jolo.

1. Ose abuwe maa n mu ara wa
   A. dudu
   B. hunjo
   C. jolo
   D. tutu
2. Iru ose won i o dara ju fun wiwe omo titun? Ose
   A. aweda
   B. funfun
   C. lile
   D. oyinbo
3. "E ku owo lomi" ti won ki iya Seri fihan pe o sese ____
   A. Bimo
   B. Fo epo
   C. Po omi
   D. Se ose
4. Asiko wo ni iya agba lo si odo Seri?
   A. Osan
   B. Aaro
   C. Irole
   D. Oru
5. Okan lara ohun elo fun ose aweda ni
   A. Epo pupa
   B. Aso funfun
   C. Ileke
   D. Iyo
6. E ku owo lomi je ikini fun
   A. Olomo titun
   B. Olojo ibi
   C. Onigbeyawo
   D. Agbe
7. Nibo ni won ti n se ose abuwe?
   A. Oja
   B. Abule
   C. Ebu
   D. Odo
8. Ta ni iya seri ran ni ose?
   A. Iya agba
   B. Sulia
   C. Iya elepo
   D. Abeni
9. Oruko miiran fun ose aweda ni ose
   A. Abuwe
   B. Funfun
   C. Oyinbo
   D. Lubulubu.
10. Akole ti o ba ayoka yii mu ju ni
   A. Isomoloruko
   B. Ose aweda
   C. Epo fifo
   D. Omo titun

**5.0. TOPIC 5:- AKOTO ODE ONI:- Yoruba Athography**

Akoto ni ona ti a n gba ko ede Yoruba sile laye ode oni. Eyi ni ipinnu awon igbimo ti o di ofin ni odun 1974.

| | **Sipeli atijo** | **Sipeli titun** | **Aba** |
|---|---|---|---|
| *1.* | *aiya*<br>*aiye*<br>*eiye*<br>*pepeiye*<br>*eiyele* | *aya*<br>*aye*<br>*eye*<br>*pepeye*<br>*eyele* | *Ki a yo faweli I kuro nitori a kop e e.* |
| *2.* | *Iton*<br>*Ison*<br>*eron* | *Itan*<br>*Isan*<br>*Eran* | *Ki a ko "an" fun aferigipe* |
| *3.* | *iban*<br>*ahan*<br>*opan* | *ibon*<br>*ahon*<br>*opon* | *Ki a ko "on" fun afetepe ati iro miiran.* |
| *4.* | *fun u*<br>*na a*<br>*yin i*<br>*pon o*<br>*mo o* | *fun un*<br>*na an*<br>*yin in*<br>*pon on*<br>*mo on* | *Ki a fa oro-aropo-oruko eniketa eyo to n sise abo gun ti o ba je aranmupe* |
| *5.* | *gan*<br>*ofon*<br>*sun un*<br>*tana*<br>*akuyun* | *gan-an*<br>*ofon-on*<br>*sun-un*<br>*tan-an-na*<br>*akun-un-yun* | *Ki a lo ami asoropo nibi ti a bat i fa ami aranmupe gun ninu eyo oro kan* |
| *6.* | *on* | *oun* | *Ki a maa ko "oun" aropo-oruko eniketa eyo dipo "on"* |
| *7.* | *okorin*<br>*obirin*<br>*enia*<br>*lailai* | *Okunrin*<br>*obinrin*<br>*eniyan*<br>*laelae* | *Ki a maa ko ohun ti a ba pe jade lenu sile.* |
| *8.* | *e, o, s* | *e, o, s* | *Ki a ma se lo daasi tabi dooti sugbon ki a maa fa iru si won ni idi* |
| *9.* | *nlo*<br>*nbo*<br>*njeun* | *n lo*<br>*n bo*<br>*n jeun* | *Ki a ya asiwaju oro-ise soto si oro-ise kikun* |
| *10.* | *nwon*<br>*enyin*<br>*niyin*<br>*tinyin* | *Won*<br>*eyin*<br>*yin*<br>*tiyin* | *Ki a yo n kuro ninu aropo oruko nitori a ko pe e.* |
| *11.* | *Otta*<br>*Ebute-Metta*<br>*Offa*<br>*Oshogbo*<br>*Shagamu*<br>*Ogbomosho*<br>*Shaki* | *Ota*<br>*Ebute-meta*<br>*Ofa*<br>*Osogbo*<br>*Sagamu*<br>*Ogbomoso*<br>*Saki* | *Ko si isupo konsonanti ninu ede Yoruba.* |
| 12. | *na*<br>*yi*<br>*dada*<br>*ogun*<br>*oto* | *Naa*<br>*Yii*<br>*Daadaa*<br>*Oogun*<br>*Ooto* | *Ki a maa lo aami faagun. Gbogbo faweli ti a ba pen i ki a maa ko sile.* |

| | | | |
|---|---|---|---|
| | *anu*<br>*ore*<br>*are*<br>*eleyi*<br>*miran*<br>*alanu*<br>*ologbe*<br>*yo*<br>*alafia*<br>*suru*<br>*papa*<br>*olopa* | *Aanu*<br>*Oore*<br>*Aare*<br>*Eleyii*<br>*Miiran*<br>*Alaaanu*<br>*Oloogbe*<br>*Yoo*<br>*Alaafia*<br>*Suuru*<br>*Paapaa*<br>*Olopaa* | |
| 13. | *tani*<br>*kini*<br>*jeki*<br>*ewoni*<br>*wipe*<br>*gegebi*<br>*eniti*<br>*ibiti*<br>*nitoripe*<br>*nitorina*<br>*nigbati*<br>*nigbagbogbo*<br>*niwongbati*<br>*lehinti*<br>*biotilejepe* | *ta ni*<br>*ki ni*<br>*je ki*<br>*ewo ni*<br>*wi pe*<br>*gege bi*<br>*eni ti*<br>*ibi ti*<br>*nitori pe*<br>*nitori naa*<br>*nigba ti*<br>*nigba gbogbo*<br>*niwon igba ti*<br>*lehin ti*<br>*bi o tile je pe* | *Ki a ma ko won gege bi oro kan.* |

**Ise Kilaasi:- Class Work**

Di awon alafo wonyi pelu idahun ti o ye.

1. Ewo ni ko ba akoto ode oni mu?______
   A. aye
   B. aiya
   C. Ilesa
2. Akoto “aiyekoto” ni ____
   A. aiyekooto
   B. ayekooto
   C. aiyekoto
3. Bawo ni a se n ko “biotilejepe” sile lode oni? _____
   A. bio tile jepe
   B. biotile jepe
   C. bi o tile je pe
4. Gegebi ni liana akoto ode oni ni ____
   A. gegebi
   B. ge gebi
   C. gege bi
5. Iro ____ ni ki i pari oro ninu ede Yoruba. _____
   A. faweli
   B. konsonanti
   C. aranmupe

**Ise Asetilewa:- Assignment**

1. **Tun awon oro wonyi ko ni liana akoto ode oni.**
   *a.* *Olopo*
   *b.* *Nilati*
   *c.* *Oshogbo*
   *d.* *Pepieye*
   *e.* *Eyele*
   *f.* *Enia*
   *g.* *Okorin*
   *h.* *Lailai*
   *i.* *Ebutte-Meta*
   *j.* *wipe*

***TOPIC 6:- ORO-AYALO (LOAN OR BORROWED WORDS IN YORUBA)***

Oro-ayalo ni oro ti a ya wo inu ede Yoruba lati inu ede miiran. Orisirisi ede ni ede Yoruba ti ya oro. Inu ede ti won ti ya oro ju ni ede Geesi nitori pe ede Geesi ni ede ajumolo orile-ede yii.

***Apeere oro ayalo ati ede ti a ti ya won.***

1. Hausa : alubosa, alaafia, wahala, sanmo, alubarika, gejia, kadara abbl.
2. Ede Heberu : Pita, Bibeli, sinagogu, Anderu, Moose, Joanu, paradise abbl.
3. Ede Larubawa : Lemomu, yidi, musulumi, mosalasi, meka, abbl.
4. Ede Geesi : tebu/ tabili, roba, peeli, camera, botu, abbl

***Ona Ti Oro-Ayalo Gba Wo Inu Ede Yoruba***

1. **E**to oselu : komisonna, woodu, gomina, sineto, kanselo, kansu ati bee bee lo.
2. Eto oro-aje: alubosa, tuwo, saabo, ireke, kalamu, jaara, abbl.
3. Eto-esin : Bibeli, pasito, alukuraani, lemomu, diakoni, soosi, Peteru abbl
4. Eto-eko : sukuu, bairo, pensu, sooki, tisa, boodu abbl
5. Ere idaraya : boolu, refiri, goli, fiidi, poolu, teniisi abbl
6. Eto amuluudun : kaseeti, rekoodu, telifisan, redio abbl

**Ìfaramọlé Tàbí Òté Lórí Ọ̀rọ̀-Àyálò:** Òrọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá gbọ́dọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú bátànì ìró èdè Yorùbá ní àwọn ọ̀nà wọ̀nyí:

1. Ọ̀rọ̀ tí a bá yá wọ inú èdè yorùbá kò gbọdọ̀ parí pẹ̀lú kọ́ńsónáńtì
2. Ọ̀rò tí a bá yá wọ inú èdè Yorùbá kò gbọdò ní ìṣùpọ̀ kọ́ńsónáńtì.
3. A gbọ́dọ̀ fi àmì ohùn sí orí gbogbo ọ̀rọ̀ tí a bá yá wọ inú èdè Yorùbá.
4. A gbọ́dọ̀ fi kọ́ńsónáńtì tàbí fáwẹ̀lì èdè Yorùbá rọ́pò kọ́ńsónáńtì tàbí fáwẹ̀lì ọ̀rọ̀ tí a yá wọ inú èdè Yorùbá.

***ORISI ORO-AYALO***

A le pin oro-ayalo si ona meji ninu ede Yoruba.

1. Oro-Ayalo Afetiya: Eyi ni oro ti a ya wo inu ede Yoruba ni ibamu pelu bi won se n pe oro naa ninu ede ti a ti ya a.
2. Oro-Ayalo Afojuya: Eyi ni oro ti a ya wo inu ede Yoruba ni ibamu pelu bi won se n ko o sile ninu ede ti a ti ya a.

***Apeere Oro-Ayalo***

| Oro-ayalo | Afetiya | Afojuya |
|---|---|---|
| Table | Tebu | Tabili |
| Bible | Baibu | Baibu |
| Peter | Pita | Peteru |
| Esther | Esita | Esiteri |
| Deacon | Dikinni | Diaconi |
| Paradise | Paradaisi | Paradise |

| | | |
|---|---|---|
| Biro | Bairo | Biro |

***Topic 7:- Onka Yoruba Kika 300 – 400 ni ede Yoruba.***

**1 – 10**

1 – ookan

2 – eeji

3- eeta

4– eerin

5 – aarun-un

6 – eefa

7 – eeje

8 – eejo

9 – eesan-an

10 – eewaa

**10 – 100**

10 – eewaa

20 – ogun

30 – ogbon

40 – ogoji

50 – aadota

50 – ogota

70 – aadorin

80 – ogorin

90 – aadorun-un

100 – ogorun-un

**100 – 200**

100 – ogorun-un

110 – aadofa

130 – aadoje

140 – ogoje

150 – aadojo

160 – ogojo

170 – aadosan-an

180 – ogosan-an

190 – aadowa

200 – ogowaa tabi igba

200 – 300

200 – igba

210 – ewa-din-okoolenigba (ewalenigba)

220 – okoolenigba

230 – ewa-din-ojilenigba (ogbonlenigba)

240 – ojilenigba

250 – ewa-din-otalenigba (aadotalenigba)

260 – otalenigba

270 – ewa-din-orinlenigba (aadorinlenigba)

280 – orinlenigba

290 – ewa din-loodunrun (aadorun-unlenigba)

300 – oodunrun

**300 – 400**

300 – oodunrun

310 – ewa-din-okooleloodunrun

320 – okooleloodunrun

330 – ewa-din-ojileloodunrun

340 – ojileloodunrun

350 – ewa-din-otaleloodunrun

360 – otaleloodunrun

370 – ewa-din-orinleloodunrun

380 – orinleloodunrun

390 – ewa-din-irinwo

400 – irinwo

**301 – 310**

301 – okanleloodunrun

302 – ejileloodunrun

303 – etaleloodunrun

304 – erinleloodunrun

305 – arun-din-ewaleloodunrun

306 – erin-din-ewaleloodunrun

307 – eta-din-ewaleloodunrun

308 – eji-din-ewaleloodunrun

309 – okan-din-ewaleloodunrun

310 - ewaleloodunrun

**Topic 8:- Oro-Oruko**

Oro-oruko ni oro to n toka si oruko eniyan, eranko, eye, ilu tabi ibikan, nnkan ayika ati bee bee lo.

***Apeere Oro-Oruko***

1. Oruko eniyan:- Bolaji, Asake, Ojuolape, Oluwadarasimi, Ayomide, bolanle, Olajide, Alabi, Taiwo, Ojo ati bee bee lo.

2. Oruko ilu:- Osogbo, Ibadan, Eko, Ilorin, Abuja, Lokoja, Ile-Ife, Kaduna, Sokoto, Ofa, Abeokuta, Sagamu ati bee bee lo.

3. Oruko eranko-ile:-

| Yoruba | English |
|---|---|
| Aja | Dog |
| Elede | Pig |
| Ewure | Goat |
| Aguntan | Sheep |
| Agbo | Ram |
| Obuko | He goat |
| Rakunmi | Camel |
| Esin | Horse |
| Ketekete | Donkey |
| Maluu | Cow |
| Ehoro ile | Rabbit |

4. Eranko igbo

| Yoruba | English |
|---|---|
| Eku | Rat |
| Okete | Rabbit |
| Okere | Squirrel |
| Oya | Grass cutter |
| Etu | Antelope |
| Agbonrin | Deer |
| Kinniun | Lion |
| Ekun | Tiger |
| Eta | Wild dog |
| Obo | Monkey |

| | |
|---|---|
| Ejo | Snake |
| Igbin | Nail |
| Ijapa | Tortoise |
| Erin | Elephant |
| Efon | Buffalo |
| Ooni | Crocordile |
| Alakan | Crab |
| Eja | Fish |
| Ede | Crayfish |

5. Eye- Ile – Domesric Birds

| Yoruba | English |
|---|---|
| Adie | Hen |
| Pepeye | Duck |
| Eyele | Pigeon |
| Ayekooto/odidere | Parrot |
| Tolotolo | Turkey |
| Akuko | Cock |

6. Eye-igbo – wild birds

| Yoruba | English |
|---|---|
| Asa | Hawk |
| Orofo | Wild pigeon |
| Ega | Palm bird |
| Aparo | Bush fowl |
| Okin | |

| | |
|---|---|
| Adaba | Dove |
| Igun | Vulture |
| Idi | Eagle |
| Owiwi | Owl |
| Ogongo | Ostrich |

7. Awon Nnkan Ayika:Objects

| Yoruba | English |
|---|---|
| Iwe | Book |
| Aga | Chair |
| Tabili | Table |
| Apoti | Stool |
| Obe | Knife |
| Sibi | Spoon |
| Omi | Water |
| Obe | Soop |
| Isu | Yam |
| Iyan | Pounded yam |
| Ogede | Banana |
| Ibepe | Pawpaw |
| Akara | Beans cake |
| Ewa | Beans |
| Igi | Tree |
| Epo pupa | Palm oil |
| Ile | house |
| Baluwe | Bathroom |
| Ile idana | Kitchen |
| Ile iwe | Bathroom |
| Ile-eko | School |
| Oba | King |
| Oluko | teacher |
| Akekoo | Student |
| Eni | Mat |
| Ikoko | Pot |
| Agbon | Basket |
| Okuta | Stone |
| Apata | Rock |

8. Orisi Oro-Oruko

a. Oruko aseeka:- countable noun

| Yoruba | English |
|---|---|
| Iwe | Book |
| Eni | Mat |
| Aga | Chair |
| okuta | Stone |
| Ada | Cutlass |
| Oko | Hoe |
| Igo | Bottle |

| | |
|---|---|
| Igi | Tree |
| Ile | House |
| Obe | Knife |
| Rula | Ruler |
| Aso | Cloth |

b. Oruko Aiseeka:- Uncountable Noun

| Yoruba | English |
|---|---|
| Iyo | Salt |
| Epo | Palm oil |
| Ororo | Vegitable oil |
| Ata | Pepper |
| Erupe | Sand |
| Omi | Water |
| Iresi | Rice |
| Obe | Soup |
| Ose | Soap |
| Ina | Fire |

c. Oruko aridimu: - concrete noun

| Yoruba | English |
|---|---|
| Aga | Chair |
| Iwe | Book |
| Ile | House |
| Igi | Tree |
| Owo | Money |
| Tbili | Table |
| Owo | Broom |
| Obe | Knife |
| Ibusun | Bed |

d. Oruko Afoyemo:- Abstract Noun

| Yoruba | English |
|---|---|
| Ogbon | Wisdom |
| Imo | Knowledge |
| Oye | Understanding |
| Eko | Education |
| Ayo | Joy |
| Ekun | Weeping |
| Erin | Laughter |
| Ife | Love |
| Igberega | Pride |
| Oyaya | Kindness |
| Iberu | Fair |
| Igbagbo | Faith |
| Adura | Prayer |
| Ibukun | Blessing |

e. Oruko Adaje:- Proper Noun

| Yoruba | English |
|---|---|
| Bola | A name |
| Olajide | A name |
| Olasupo | A name |
| Kehinde | A name |
| Ibadan | A town |
| Osogbo | A town |
| Ojo abameta | Saturday |
| Seere | January |
| erele | February |

f. Oruko Ajumoje:- Common Noun

| Yoruba | English |
|---|---|
| Oluko | Teacher |
| Akekoo | Student |
| Obi | Parent |
| Oba | King |
| Adajo | Lawyer |
| Dokita | Doctor |
| Agbe | Farmer |
| Omode | Ghild |
| Oko | Husband |
| iyawo | wife |
| Agbalagba | Elder |
| Okunrin | Man |
| Obinrin | Woman |
| Iya | Mother |
| Baba | Father |
| Egbon | Elder brother/ sister |
| Aburo | Younger brother/ sister |
| Ako | Male |
| Abo | Female |

Ise Oro-Oruko

Ise meta ni oro-oruko maa n se ninu gbolohun ede Yoruba.

a. Oluwa: Oro-oruko maa n se ise oluwa ninu gbolohun. Bi apeere:
   i. **Idowu** gun igi.
   ii. **Oladele** ra epa je.
   iii. **Alaba** sun.
   iv. **Ewure** je isu won.
   v. **Aja ode** pa etu ni ana.

b. Abo:- Oro-oruko maa n se ise abo ninu gbolohun. Bi apeere:
   i. Jide mu **omi.**
   ii. Alaba ka **iwe re**.
   iii. Won ra **keke titun.**
   iv. A fo **aso wa**.
   v. Aina feran ere **idaraya.**

c. Eyan:- Modifier: Oro-oruko maa n se ise eyan ninu gbolohun. Bi apeere:
   i. Iya **Iyabo** gba a nimoran.
   ii. Aja **ode** pa eran **oya**.
   iii. Ko si ise **ijoba** lode.
   iv. Aso **olopa** naa ti doti.
   v. Ile **oba** to jo, ewa lo bus i i.

Ise Kilaasi :-Class Work

Di awon alafo wonyi pelu idahun ti o ye.

1. Oruko eranko ni _____
   A. Kola
   B. Ewure
   C. Asake
2. Oro-oruko to sise oluwa ninu, “Aja gbe eegun eran”, ni _____
   A. Eran
   B. Eegun
   C. Aja
3. “Baba Ajala ra bata titun”. Oro-oruko to sise eyan ninu gbolohun yii ni_____
   A. Ajala
   B. Baba
   C. Bata
4. Oro-oruko aseeka ni awon wonyi ayafi ____
   A. Epo
   B. Omi
   C. Aga
5. Ewo ni oro-oruko afoyemo ninu awon wonyi? _____

A. Ada
B. Ibukun
C. Iwe

**Ise Asetilewa : Assignment**

1. Ko oro-oruko ajumoje marun-un sile ni ede Yoruba.
2. Ko oruko eranko igbo marun-un sile.

**Topic 9:- Oro-Aropo-Oruko**

ORO-AROPO-ORUKO

Eyi ni oro ti a n lo dipo oro-oruko ninu ede Yoruba.

Bi apeere:

1. <u>Mo</u> je isu.
2. Alaba n pe <u>o</u>.
3. <u>Won</u> feran awon omode.
4. Aso <u>re</u> ti doti.

Oro-aropo-oruko ni a fa ila si ninu gbolohun oke yii.

Orisi Oro-Aropo-Oruko

A le pin oro-aropo-oruko si ona meta nipa iye:

1. Aropo Oruko Enikinni
   a. Eyo: Singular
      i. Mo: <u>Mo</u> je agbado sisun ni ale ana.
      ii. N: <u>N</u> ko lo si ile-eko ni ijeta.
      iii. Mi; Oluko n pe <u>mi</u>
   b. Opo: Plural
      i. A: <u>A</u> ko ile si ilu Eko.
      ii. Wa: Oluko fe ri <u>wa</u>
2. Aropo-Oruko Enikeji
   a. Eyo: Singular
      i. O: <u>O</u> ko se ise asetilewa.
      ii. O: Oluko n pe <u>o</u>.
      iii. O: Ademola fe ri <u>o</u>
      iv. Re: Yara **<u>re</u>** ni iwe mi wa
   b. Opo: Plural
      i. E: **<u>E</u>** ma se alaiwa ni ola.
      ii. Yin: aso ile-eko **<u>yin</u>** ti doti.
3. **Aropo-Oruko-Eniketa**
   a. Eyo: Singular.
      i. O: **<u>O</u>** wa ni yara ikawe.
      ii. Re: Aja **<u>re</u>** pa etu.
      iii. Gbogbo faweli oro-ise
         Aja pa eku : Aja pa **<u>a</u>**
         Jide ge igi : O ge **<u>e</u>**
         Alaba na Ojo: O na **<u>a</u>**
   b. Opo: plural
      i. Won : **<u>Won</u>** fe mu omi.
      ii. Won: Oluko n pe **<u>won</u>**.

Ise Oro-Aropo-Oruko: Ise meta ni oro-aropo-oruko n se ninu ede Yoruba:

1. Oluwa: Object of a sentence
   a. **<u>Mo</u>** ra epe ati ogede je.
2. Abo : object of a sentence
   a. Oluko n pe **<u>yin</u>**..
3. Eyan: Modifier
   a. Adebisi wa ni yara **<u>re</u>**.

**Oro-Aropo-afarajoruko**

Eyi ni oro ti isesi ati ihuwasi won fi ara jo oro-oruko ninu gbolohun.

**Iyato Laarin Oro- Aropo-Oruko ati Aropo-Afarajoruko**

1. A le se akiyesi alatenumo fun aropo-afarajoruko sugbon a ko le se eyi fun oro-aropo-oruko. Bi apeere:
   a. Emi ni mo ni aso.
   b. Iwo ni o n pariwo.
2. A le fi oro asopo so aropo-afarajoruko po sugbon eyi ko se e se fun aropo-oruko.
   a. Awa ati eyin lo si oja oba.
   b. Oun pelu eyin feran ere idaraya.
3. Oro-aropo-afarajoruko le gba eyan ṣugbọn

3. Aropo-afarajoruko Eniketa
   a. Eyo: Singular
      Oun ko feran ariwo.
   b. Opo: Plural
      Oluko n pe awon.

Ise Aropo-Afarajoruko

Ise meta ni aropo-afarajoruko maa n se ninu ede Yoruba.

1. Oluwa: Object of a sentence
   Awa pa eran ti o tobi pupo.
   Oun ko fe wa si ile-eko.
   Eyin le n pariwo.
2. Abo: Object of a sentence.
   Oluko n wa eyin.
   Bola fe ri emi.

| | |
|---|---|
| aropo-oruko ko le gba eyan.<br>a. Awa naa fe je ibepe pipon.<br>b. Emi gan-an feran emu ope.<br>Orisi Oro-Aropo-Afarajoruko<br>1. Aropo-Afarajoruko Enikinni.<br>a. Eyo Singular<br>Emi: Emi lo si oja.<br>b. Opo: Plural<br>Awa ko je gbegiri tutu.<br>2. Aropo-Afarajoruko Enikeji<br>a. Eyo: Singular<br>Iwo feran ariwo pipa.<br>b. Opo: Plural<br>Eyin ko gbodo ma wa. | Alaba pade mi lona oja.<br>3. Eyan: Modifier<br>Ile-eko awa tobi pupo.<br>Bata iwo dudu.<br>Aso oun ti doti. |

***TOPIC 10:- OWO SISE ATI IPOLOWO OJA.***

Ipolowo oja je ona ti awon Yoruba n gba so fun awon eniyan nipa oja ti won n ta. Iru oja bee le je ire oko bi I agbado, isu, ege, orombo, ogede wewe, ogede agbagba, ata rodo, ege tabi gbaguuda, anamo ati bee bee lo. O si le je oja ate bi i isana, iyo, alubosa, ose iwe, epo pupa, bata, aso, eni, iru, abo ati bee bee lo.

**Ona Ipolowo Oja Laye Atijo**

Ona meta ni awon Yoruba n gba polowo oja laye atijo.

**1.Ipate:-** Eyi ni ki a to oja si ibi ti awon eniyan ti le ri I ti won yoo si fe leti ra iru oja bee. Ona meta ni won maa n pate oja si laye atijo.

a. Ipate oja si oju ona:- awon Yoruba a maa pate oja si oju ona laye atijo. Oju ona bee le je ona ti awon eniyan n gba lo si oko tabi lo si oja. Bi won ba pate oja si oju ona won a maa fi okuta so iye ti won n ta ile kookan. Eni ti o f era oja yoo ko oja to ra yoo si fi owo oja sinu agolo tabi apo. Bi oloja ba de ni irole yoo ko owo re yoo si pale oja to seku mo.
b. Ipate oja sinu soobu:- awon Yoruba a tun maa pate oja sinu soobu won. Iru soobu bee le wa niwaju ile. Oja ounje bi i ata, ewa, iresi, alubosa, magi, eja, ponmo, iyo, epo-pupa ati bee bee lo ni won saba maa n pate siwaju ile.
c. Ipate oja ninu oja:- Awon Yoruba a maa pate oja won si inu oja laye atijo. Iru oja bee le je aso, bata, ohun elo idana, ohun elo ikole ati bee bee lo.

**2.Ikiri:**- Eyi ni ki a gbe oja wa le ori ki a si maa lo lati adugbo kan si adugbo keji lati fi ohun enu polwo oja ti a n ta. Orisirisi ipede ni awon to n kiri oja maa n lo. Bi apeere:

| Oja | Ipolowo |
|---|---|
| Agbado | Langbe jinna o. |
| Ewa | Lamuluke ewa. |
| sise | Isu epo muye. |
| Isu sise | Ereja esebe o. |
| Eja | Yere re epa ree. |
| Epa | Ofe niresi eran lowo. |

| | |
|---|---|
| Iresi | Arokun epo oyinbo. |
| Kerosin | Ebo toro ogede. |
| Ogede | Oyin ladun osan o. |
| Oronbo | Kengbe iya o. |
| Iyan | Kengbe amala. |
| Amala | Oori bi ike |
| Eko jije | Kengbe eba. |
| Eba | Moin-moin epo oole rodo |
| Moin- | Ayangbe gaari o. |
| moin. | Ila oloko gboro o |
| Gaari | Awusa yi gbo keke bi obi. |
| Ila | O gbo o agbola. |
| Awusa | Eleyin ni n wa o ko welerigi. |
| | Elerigi abenu fifo |

**3.Lilo ogbon ewe lati polowo oja**:- Eyi je ogbon ti awon oloja maa n da lati fa oju onibaara mora. Apeere ogbon ipolowo oja ni:

**a. Itowo**:- Eyi ni ki a to oja ti a fe ra wo ki a le mo bi o se ri ni enu ki a to ra a. Apeere oja ti a le towo ni: epa, gari, oronbo, emu,  suya, iru, ati bee bee lo.

**b. Isiwo**:- eyi maa n waye nigba ti a ba si oja ti a fe ra wo ki a le mo bi oju re se dara si. Iru oja bee le je iyan, eba, amala, moin-moin, eko jije ati bee bee lo.

**d.  Eni**:- Eni je oja die ti oloja fi si oja ti a ra lowo re. o fere ma si oja ti won ko le fi eni si paapaa julo bi eniyan bar a oja pupo. Apeere oja ti won maa n fi eni si ni gaari, iresi, ewa, ata, alubosa, oronbo, epa, agbado, iyo, iru, ati bee bee lo.

**e. Gbanjo**:- Gbanjo je ona ti won n gba ta oja ni owo pooku. Won yoo da oja sile ti won yoo si din owo re ku.

**IPOLOWO OJA LAYE ODE ONI**

Orisiirisii ona ni awon eniyan n gba polowo oja laye ode oni. Die lara awon ona naa ni;

a. Ipolowo oja lori redio
b. Ipolowo oja ninu telifisan.
c. Ipolowo oja ninu iwe iroyin.
d. Ipolowo oja lori ero ayelujara
e. Ipolowo oja nipa lilo iwe ilewo
f. Ipolowo oja nipa lilo aroko ikede.
g. Ipolowo oja nipa lilo ero gbohungbohun
h. Ipolwo oja nipa fifi oko tabi alupupu kiri.
i. Ipolowo oja nipa tita rafulu.
j. Ipolowo oja nipa lilo eni igbalode.
k. Ipolowo oja nipa lilo bonanza

| | |
|---|---|
| **Ise Kilaasi : Class Work** | Di awon alafo wonyi pelu idahun ti o ye. |

1.”Langbe jinna o” je ipolowo ___
A. isu
B. oronbo
C. agbado
2.Bawo ni a se n polowo ila? _____
A. ila oloko gboro o
B. Ofe niresi eran lowo
C. lamuluke ewa.
3. Oja ti a le towo ni awon wonyi ayafi _____
A. iyan
B. epa
C. orombo
4. lilo lati adugbo kan si ikeji lati ta oja ni_____
A. isiwo
B. ikiri
C. eni
5. ipolowo oja lode oni ni awon wonyi ayafi_____
A. gbanjo
B. redio
C. bonanza

**Ise Asetilewa – Assignment**

1.Daruko ona meta ti awon Yoruba n gba pate oja won laye atijo.
2. Ko ona ipolowo oja meje sile laye ode oni.

## TOPIC 11: ÌṢẸ̀DÁ Ọ̀RỌ̀-ORÚKỌ

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa kíkan mófîìmù méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ pọ̀ mọ́ ara wọn.

MỌ́FÎÌMÙ: Mọ́fîìmù ni ègé tí ó kéré jùlọ tí a lè pín ọ̀rọ̀ kan sí pẹ̀lú ìtumọ̀ kíkún. Ó lè jẹ́ ìtumọ̀ àdáni tàbí ìtumọ̀ gírámà.

ORÍṢI MỌ́FÎÌMÙ: A lè pín mọ́fîìmù sí ọ̀nà méjì ní èdè Yorùbá.

**Mọ́fîìmù Adádúró**: Èyí ni odidi ọ̀rọ̀ tí́ ó lè dá dúró pẹ̀lú ìtumọ̀ kíkún. A kò lè tún irú ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ pín mọ́. Bí àpẹẹrẹ ilé, ọmọ, ajá, àdá, ọjà, aṣọ, bàtà, ọkọ́, àdá, orí, ẹnu, òkúta, ṣíbí, ewúrẹ́, ọba, ọ̀gẹ̀dẹ̀, agbọ̀n, iyán, ojú, fèrèsé, ọkùnrin, owó, ìlẹ̀kùn, ìgò, odó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Mọ́fîìmù Afarahẹ:** Èyí ni mọ́fîìmú tí kò ní ìtumọ̀ àdáni. Kò lè dá dúró àfi bí ó bá fi ara hẹ mọ́fîìmù adádúró. Ìtumọ̀ gírámà nìkan ló máa ń ní. A tún lè pè é ní àfòmọ́. A lè pín in sí àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀, àfòmọ́ àarin àti àfòmọ́ ìparí.

**Àfòmọ́ Ìbẹ̀rẹ̀:** Èyí ni mọ́fîìmù tí a máa ń so mọ́ ìbẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀. Bí àpẹẹrẹ: a, e, i, o, ọ, ẹ, oní, àti, òn, àì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Àfòmọ́ Àarin:** Èyí ni mọ́fîìmú tí a máa ń so mọ́ ọ̀rọ̀ ní àarin. Bí àpẹẹrẹ: kí, dé, ji.

**Àfòmọ́ Ìparí:** Èyí ni mọ́fîìmù tí a máa ń so mọ ìparí ọ̀rọ̀.

## ÀWỌN Ọ̀NÀ TÍ A Ń GBÀ ṢẸ̀DÁ Ọ̀RỌ̀-ORÚKỌ

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa lílo àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ pọ̀ mọ́ ọ̀rọ̀-ìṣe. Bí àpẹẹrẹ:

| Àfòmọ́ Ìbẹ̀rẹ̀ | Ọ̀rọ̀-Ìṣe | Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá |
|---|---|---|
| a | Dé | adé – crown |
| a | Yọ̀ | ayọ̀ – joy |
| À | Ṣẹ | àṣẹ – authority |
| È | Lò | èlò - ingredent |
| È | Jó | èjó – charcoal |
| Ì | Jà | ìjà – fight |
| I | Kú | ikú – death |
| Ì | Lé | ìlé – pack |
| Ò | Kú | òkú – corps |
| Ọ̀ | Lẹ | Ọ̀lẹ – laziness |
| Ọ | Dẹ | Ọdẹ – hunter |
| Òǹ | Kà | Òǹkà – number |
| Àì | Jẹ | Àìjẹ – not eatable |
| Àì | Sùn | Àìsùn – not sleeping |
| Àti | Jẹ | Àtijẹ – act of eating |
| Àti | Mu | Àtimu –act of drinking |

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa lílo àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ oní pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ. Bí àpẹẹrẹ:

| **Àfọ̀mọ́ ìbẹ̀rẹ̀** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá** |
|---|---|---|
| Oní | Ilé | Onílé |
| Oní | Igi | Onígi |
| Oní | Ìṣẹ́ | Oníṣẹ́ |
| Oní | Ẹja | Ẹlẹja |
| Oní | Ọjà | Ọlọ́jà |
| Oní | Ayọ̀ | Aláyọ̀ |

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa lílo àfọ̀mọ́ ààrin pẹ̀lú ọ̀rọ̀-orúkọ. Bí àpẹẹrẹ:

| **Ọ̀rọ̀-orúkọ** | **Àfòmọ́ ààrin** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá** |
|---|---|---|---|
| Ọmọ | Kí | Ọmọ | ọmọkọ́mọ |
| Ilé | Ji | Ilé | iléjilé |
| Oko | Dé | Oko | okodóko |

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa àpètúnpè ọ̀rọ̀-orúkọ

| **Ọ̀rọ̀-orúkọ** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá** |
|---|---|---|
| Ọdún | Ọdún | Ọdọọdún |
| Oṣù | Oṣù | Oṣooṣù |
| Ọ̀sẹ̀ | Ọ̀sẹ̀ | Ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ |
| Ojúmọ́ | Ojúmọ́ | Ojoojúmọ́ |
| Alẹ́ | Alẹ́ | Alaalẹ́ |

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa àpètúnpè ọ̀rọ̀-ìṣe. Bí àpẹẹrẹ:

| **Ọ̀rọ̀-ìṣe** | **Ọ̀rọ̀-ìṣe** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá** |
|---|---|---|
| Wolé | Wolé | Woléwolé |
| Paná | Paná | Panápaná |
| Gbọ́mọ | Gbọ́mọ | Gbọ́mọgbọ́mọ |
| Pẹja | Pẹja | Pẹjapẹja |

A lè ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀-orúkọ nípa ìsúnkì odidi gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ:

| **Gbólóhùn** | **Ọ̀rọ̀-orúkọ tí a ṣẹ̀dá.** |
|---|---|
| Ifá ní etí. | Ifálétí |
| Ayọ̀ dé ilé. | Ayọ̀délé |
| Olúwa dára sí mi. | Olúwadárasimi |
| Adé wá ilé. | Adéwálé. |

**TOPIC 12: ÀRÒKỌ KÍKỌ**

Àròkọ kíkọ jẹ́ ọ̀nà tí a ń gbà fi èrò inú ẹni hàn lórí orí-ọ̀rọ̀ kan nípa kíkọ sílẹ̀.

Orísi Àròkọ

| Orịsi Aròkọ | Apẹẹrẹ |
|---|---|
| Aroko alapejuwe | Ile-eko mi<br>Ounje ti mo feran ju.<br>Ore mi ti mo feran ju.<br>Aafin oba ilu mi.<br>Iru ile ti mo fe ko. |

| | |
|---|---|
| Aroko alalaye / ajemo-isipaya | Omi<br>Ise agbe<br>Okunfa iku odo.<br>Bi mo ba je aare orile ede yii.<br>Asa iranra-eni-lowo.<br>Ere iadaraya. |
| Arokọ oniroyin. | Ijanba oko kan to soju mi<br>Igbeyawo egbon mi to waye laipe.<br>Ija igboro kan to soju mi.<br>Ija igboro awon odo odun 2020. |
| Aroko Alariiyanjiyan | Omokunrin wulo ju omobinrin lo.<br>Ise agbe dara ju ise dokita lo<br>Ise adani san ju ise ijoba lo.<br>Ki eniyan koko kole san ju ki eniyan koko ra moto lo.<br>Ile-eko aladaani dara ju ile-eko ijoba lo. |
| Aroko onisorogbesi | Anfaani eko ofe<br>Ijoba alagbada.<br>Asa isomoloruko.<br>Owongogo ounje. |

ÌGBÉṢẸ̀ ÀRÒKỌ

a. Orí-ọ̀rọ̀ – heading
b. Ìfáàrá – introduction.
c. Kókó àròkọ – body of the essay.
d. Ìkádìí tàbí ìgúnlẹ̀ – conclusion.

Àpẹẹrẹ Àròkọ

**a. Ilé-Ẹ̀kọ́ Mi.**

Orúkọ ilé-ẹ̀kọ mi ni Regina Pacis
Ilé-ẹ̀kọ́ náà wà ní Garki 2 Àbújá.
Ilé-ẹ̀kọ́ náà jẹ́ ilé-ẹ̀kọ́ àwọn obìrin.
Àpótí ìfiwéránṣẹ́ ilé-ẹ̀kọ́ mi ni 4868.
Ilé-ẹ̀kọ́ aládàáni ni Regina Pacis College.
Ilé-ẹ̀kọ́ ni àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ń gbé ní Regina Pacis.
Yàárá ìkówèépamọ́sí wà ní ilé-ẹ̀kọ́ náà.
Omi ẹ̀rọ àti iná mọ̀nàmọ́ná wà pẹ̀lú.
A ni yàárá ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì pẹ̀lú ilé àwọn akẹ́kọ̀ọ́
Akẹ́kọ̀ọ́ bíi ẹgbẹ̀rin ló wà ní ilé-ẹ̀kọ́ náà.
A ní olùkọ́ bíi àádọ́rin.
Ilé ńlá bíi méjìla àti Yàárá ìkàwé méjìléláàdọ́ta ló wà níbẹ̀
Mo fẹ́ràn ilé-ẹ̀kọ́ náà nítorí àwọn olùkọ́ wa múra ṣíṣẹ́.

**b. Àròkọ Oníròyìn**

**Ìjàǹbá Ọkọ̀ Kan Tó Ṣojú Mi**

Ìjàǹbá náà wáyé ní ọjọ́ kẹ̀rìnlá oṣù kejì ọdún 1992.
Ìjàǹbá náà ṣẹlẹ̀ ní ojú ọ̀nà Àbùjá sí Gúágúáládá.
Ní déédé agogo mẹ́jọ alẹ́ ni ìjàǹbá náà ṣẹlẹ̀.

Èrò mẹ́fà ló wà nínú ọkọ̀ náà.
Ó kù díẹ̀ kí á dé Gìrí ni ìjàǹbá náà ṣẹlẹ̀.
Ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ kan ló déédé jánà mọ́ ọkọ̀ wa lẹ́nu.
Ọkọ̀ tí a wọ̀ kó bíréèkì ṣùgbọ́n ẹ̀pa kò bóró mọ́.
Gbàà ni a gbọ́ tí ọkọ̀ wa kọlu ọkọ̀ kejì.
Ìgbà méjì ni ọkọ̀ wa tàkìtì kí ó tó dúró.
Àwọn tí wọ́n ń ta ọjà ní ẹ̀gbẹ́ ọ̀nà ni wọ́n sáré yọ èrò nínú ọkọ méjèèjì.
Ènìyàn mẹ́rin ló fara pa.
A sáré kó àwọn tó farapa dà sínú ọkọ̀ mîìràn.
A sì gbé wọn lọ sí ilé ìwòsàn ìjọba ní Gúágúáládá.

## ÀWỌN ÌBÉÈRÈ FÚN ÌGBÁRADÌ – LIKELY EXAMINATION QUESTIONS

## FIRST TERM EXAMINATION YORUBA LANGUAGE JSS 3 DURATION: 1 ½ HOUR

## SECTION A: OBJECTIVES

## INSTRUCTION: ANSWER ALL QUESTIONS IN THIS SECTION

**AKAYE: Ka ayoka isele yii ki o si dahun ibeere ti o tele e.**

Asa ounje se pataki pupo nile Yoruba. Apeere ounje ile Yoruba ni isu. Orisirisi ounje ni a le ri lati ara isu. Bi apeere iyan, amala, asaro, ojojo, dundu ati bee bee lo. Ounje miiran nile Yoruba ni agbado. Lara agbado ni a ti maa n ri eko, abari, egbo, aadun ati bee bee lo. ounje miiran ni ogede agbagba. A le ri amala ogede, dodo, ipekere ati booli lati ara ogede agbagba.

Paki, ege tabi gbaguuda tun je ounje miiran laarin awon Yoruba. Ege ni a fi n se gaari, eba, fuufu, oka lafun ati bee bee lo. Ewa tun je ounje Pataki laarin awon Yoruba. A le ri akara, moin-moin, ewa riro, adalu ati ekuru lati ara ewa. Awon ounje miiran ni koko, esuru, anamo, ewura ati bee bee lo. A le fi koko ati ewura gun iyan, sugbon a kii fi esuru tabi anamo gun iyan.

Iyan jije wopo laarin awon Ekiti, Ijesa ati awon Oyo. Oka lafun wopo laarin awon Egba ati Saki.

Dahun Ibeere 1 – 10

1. Ohun to se Pataki laarin awon Yoruba ni ___
   A. Ounje
   B. Ija
   C. Eebu
   D. Awada
2. Ewo ni a le ri lati ara isu ninu awon wonyi?
   A. Ewa
   B. Akara
   C. Eko
   D. Iyan
3. Iru ounje wo ni dundu?
   A. Yam porridge
   B. Yam cake
   C. Roasted yam
   D. Fried yam
4. A le ri awon ounje wonyi lara agbado ayafi___
   A. Amala
   B. Eko
   C. Abari
   D. Egbo
5. Ki ni a fi n se gaari?
   A. Agbado
   B. Ege
   C. Ewa
   D. Isu
6. Ewo ni a ko le fi gun iyan?
   A. Esuru

B. Koko
C. Ewura
D. isu

7. Ogede agbagba tumo si __
   A. Potato
   B. Plantain
   C. Cocoyam
   D. Kolanut
8. Iyan jije wopo laarin awon wonyi ayafi ___
   A. Oyo
   B. Ijesa
   C. Ekiti
   D. Hausa
9. A le ri ounje wonyi lati ara ewa ayafi ____
   A. Moin-moin
   B. Ekuru
   C. Abari
   D. Akara
10. Akole ti o ba ayoka yii mu ju ni ___
   A. Asa ounje nile Yoruba
   B. Ere idaraya nile Yoruba
   C. Oge sise nile Yoruba
   D. Asa isomoloruko.
11. Orirun awon Yoruba ni ___
   A. Ile-Ife
   B. Osogbo
   C. Ibadan
   D. Ilesa
12. Baba oduduwa ni ___
   A. Agbonniregun
   B. Lamurudu
   C. Oranmiyan
   D. Obasanjo
13. Okanbi bi omo ___
   A. Mefa
   B. Meje
   C. Mejo
   D. Mesan-an
14. Eni to jogun ile ninu awon omo Okanbi ni ___
   A. Olowu
   B. Oranmiyan
   C. Alaketu
   D. Orangun
15. Akobi ninu awon omo Okanbi ni ___
   A. Olowu
   B. Olupopo
   C. Onisabe
   D. Orangun
16. Ta lo te ilu Oyo do ninu awon omo Oranmiyan?
   A. Oba Bini
   B. Alaketu
   C. Oranmiyan
   D. Onisabe
17. Oruko oye oba ilu ile-Ife ni ___
   A. Alake
   B. Ooni
   C. Alaafin
   D. Orangun
18. Ojo meloo ni Oduduwa fi rin de Ile-Ife lati ilu Meka?___ Ojo
   A. Aadorun-un
   B. Ogorin
   C. Aadorin
   D. Ogota
19. Omo Oduduwa ni___
   A. Awolowo
   B. Obasanjo
   C. Tinubu
   D. Okanbi
20. Eni ti o je oba ni ilu Ile-Ife ki Oduduwa to de ni ___
   A. Agbonniregun
   B. Oranmiyan
   C. Olowu
   D. Olupopo
21. Apapo faweli ede Yoruba je ___
   A. Mejila
   B. Metala
   C. Merindinlogun
   D. Ogun
22. Konsonanti ni awon wonyi AYAFI___
   A. /w/
   B. /k/
   C. /r/
   D. /a/
23. Ewo ni afeyinfetepe ninu awon wonyi?

A. /b/
B. /f/
C. /r/
D. /d/

24. Faweli aarin ninu awon wonyi ni ___
 A. /a/
 B. /i/
 C. /e/
 D. /o/
25. Awon wonyi ko si ninu ede Yoruba AYAFI __
 A. K
 B. V
 C. Z
 D. X
26. Leta kefa ninu alifabeeti ede Yoruba ni ___
 A. M
 B. B
 C. K
 D. F
27. Faweli aranmupe ni ___
 A. b
 B. a
 C. g
 D. on
28. faweli iwaju ni awon wonyi ayafi__
 A. /e/
 B. /i/
 C. /u/
 D. /in/
29. Good morning tumo si
 A. E kaasan
 B. E ku irole
 C. E kale
 D. E kaaaro
30. Bawo ni a se n ki onigbeyawo?
 A. E ku inawo iyawo
 B. E ku ewu omo
 C. E ku inawo ile
 D. E ku ojobii.
31. **Hunter** ninu awon wonyi ni ise ___
 A. Agbe
 B. Akope
 C. Ode
 D. Oluko
32. Ewo ni kii se ise ibile Yoruba? Ise __
 A. Aso hihun
 B. Onidiri
 C. Oluko
 D. Agbede
33. Ohun elo ise agbe ni awon wonyi **ayafi**___
 A. Akoro
 B. Agbon
 C. Oko
 D. Iwe
34. Igbese akoko ninu asa igbeyawo ni ____
 A. Idana
 B. Alarina
 C. Ifojusode
 D. Itoro
35. Agbenuso laarin oko ari iyawo ni ___
 A. Alarina
 B. Baba iyawo
 C. Ore iyawo
 D. Oko iyawo
36. Ohun elo igbeyawo ni awon wonyi **AYAFI**___
 A. Ireke
 B. Ataare
 C. Obi
 D. Obe
37. Igbeyawo ibile ni awon wonyi AYAFI igbeyawo___
 A. Nisu loka
 B. Agbagba
 C. Asante
 D. Kootu
38. Pepeiye ni liana akoto ode oni ni ___
 A. Peipeye
 B. Pepeye
 C. peipeiye
 D. peyepe
39. Ewo ni ko ba akoto ede Yoruba mu?
 A. Osogbo
 B. Ilesa
 C. Ogbomosho
 D. Folasade
40. Odun ____ ni ijoba apapo fowo si abajade igbimo to sise lori akoto ede Yoruba.
 A. 1974

B. 2009
C. 2020
D. 2024

41. Eya Yoruba to ni ekun-iyawo ni ___
    A. Oyo
    B. Ijesa
    C. Egba
    D. Ekiti
42. Litireso apileko ni ___
    A. Oral literature
    B. Written literature
    C. Prose
    D. Drama
43. Apeere litireso alohun ni ___
    A. Ijala
    B. Ogede
    C. Isu
    D. Iyan
44. Orisa to ni sango-pipe ni
    A. Ogun
    B. Sango
    C. Oya
    D. Esu
45. Litireso alohun to je mo orisa osun ni
    A. Iwi
    B. Rara
    C. Osun-pipe
    D. Iyere-ifa
46. Oro-oruko maa n se ise ____ ninu ede Yoruba.
    A. Meta
    B. Merin
    C. Marun-un
    D. Mefa
47. Ninu "**Ade je iresi sise**" oro-oruko to sise oluwa ni
    A. Je
    B. Ade
    C. Iresi
    D. Sise
48. Oro-oruko aseeka ni awon wonyi **AYAFI**
    A. Iwe
    B. Ile
    C. Omi
    D. Abo
49. Ewo ni oruko afoyemo ninu awon wonyi?
    A. Aga
    B. Apoti
    C. Ilekun
    D. Alaafia
50. Toka si oruko aiseeka ninu "**Alaba je iresi pelu ore re**"
    A. Iresi
    B. Alaba
    C. Pelu
    D. Ore

**Di alafo wonyi pelu oro-ise ti o ye**

51. Idowu ____ eko ati akara.
    A. Gun
    B. Ge
    C. Je
    D. Sa
52. Kola ___ lori aga.
    A. Jokoo
    B. Sare
    C. Lo
    D. Po
53. Adekunle n ___ iwe re.
    A. Fo
    B. Ka
    C. Je
    D. Gun

**Tumo awon gbolohun wonyi si ede Yoruba.**

54. Sola wa ni yara re.
    A. Sola is in her room.
    B. Sola washed her shoes.
    C. Sola slept in her room.
    D. Sola is reading her book.
55. She came to school last week.
    A. O wa si ile-eko ni ose to koja.
    B. Won wa ni ile-eko won.
    C. Ko wa si ile-eko mo
    D. O fe lo si ile-eko.

**IDENTIFICATION OF OBJECTS**

56. Eya ara isale yii ni



A. owo
B. ese
C. kokose
D. oju

57. Ki ni oruko ti awon Yoruba n pe eranko isale yii?



A. Alangba
B. Akuko
C. Ewure
D. Aguntan

58. Ohun elo isale yii ni awon Yoruba n pe ni__



A. Igi
B. Apoti
C. Igbale
D. Iwe

59. Ki ni oruko eranko isale yii ni ede Yoruba?



A. Opolo
B. Elede
C. Alakan
D. Ehoro

60. Ki ni eya ara isale yii ni ede Yoruba?

A. Ori
B. Imu
C. Enu
D. Eti

**SECTION B: THEORY**

**ANSWER THREE (3) QUESTIONS IN THIS SECTION**

1. a. Daruko igbese igbeyawo marun-un ni ede Yoruba.
   b. Toka si awon ohun elo igbeyawo marun-un ti o mo.
2. a. Tun awon oro wonyi ko ni ilana akoto ode oni.

| Sipeli Atijo | Akoto Ode Oni |
|---|---|
| 1. Araiye<br>2. Aiya<br>3. Oshogbo<br>4. Ogbomosho<br>5. Nigbagbogbo | |

   b. Ko nomba wonyi ni onka Yoruba.

| Nomba | Onka Yoruba |
|---|---|
| 1. 50<br>2. 100 | |

| | |
|---|---|
| 3. 120<br>4. 200<br>5. 300 | |

3. a. Ya ate faweli ede Yoruba.(Draw Yoruba vowel chat)

   b. Ko oruko aiseeka marun-un ni ede Yoruba.

4. a. Toka si oro- oruko aiseeka (uncountable noun)ninu gbolohun wonyi:

   i. Won jokoo lori omi.

   ii. Alabi fi epo-pupa se obe.

   iii. Kunle je iresi pelu ore re.

   iv. Ko dara ki omode maa fi erupe sere.

   v. Aja ode je obe ti Alaba se.

   b. Ko ikini wonyi sile ni ede Yoruba:

   i. Good morning

   ii. Good afternoon

   iii. Good evening

   iv. Good night

   v. Good bye